# ÀTÚNYẸ̀WÒ SÍLÉBÙ OLÓHÙN ÒKÈ (SOO) NÍ Ẹ̀KA ÈDÈ ARIGIDI

**Samuel Obalolu OKE**
University of Ibadan, Nigeria
okesamueloba@gmail.com

**Olaide Ridwan JIMOH**
University of Ibadan, Nigeria
ridwanjimoh12345@gmail.com

**DOI : https://doi.org/10.5281/zenodo.20757033**

**Àṣamọ̀**
Sílébù Olóhùn Òkè (SOO) ni wúnrẹ̀n gírámà tó máa ń jẹyọ láàárín olùwà àti àpólà ìṣe nínú Yorùbá Àjùmọ̀lò àti àwọn ẹ̀ka èdè rẹ̀, èyí tí Arigidi jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn ẹ̀ka èdè náà. Ìmọ àtijọ́ lórí SOO ní ẹ̀ka èdè Arigidi ni pé ó jẹ́ atọ́ka afànámọ́mìí tàbí wúnrẹ̀n tí ó ń tọ́ka sí ìṣẹ̀lẹ̀ tó ti parí. Ṣùgbọ́n ẹ̀rí tuntun tí a yànnàná rẹ̀ nínú bébà yìí fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé wúnrẹ̀n náà ń ṣàfihàn àbúdà iye olùwá nínú gbólóhùn ní. Torí náà, ìrísí méjì ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ní SOO ní èdè Arigidi ní. Ìrísí àkọ́kọ́ ní 'á', èyí tí ó máa ń jẹyọ nígbà tí olùwà inú gbólóhùn bá jẹ́ ẹyọ. Ìrísí rẹ̀ kejì sì ni 'wá', tí ó máa ń jẹyọ nígbà tí olùwà bá jẹ́ ọ̀pọ̀.

**Kókó-ọ̀rọ̀*:*** Sílébù olóhùn òkè, àbùdá iye, Ìrísí, Arigidi

## 1. Ìfáàrà

Sílébù Olóhùn Òkè (SOO) ni wúnrẹ̀n tí ó máa ń jẹyọ láàárín olùwà àti ọ̀rọ̀-ìṣe nínú Yorùbá àjùmọ̀lò àti àwọn ẹ̀ka èdè rẹ̀. Àwọn onímọ̀ ti ṣiṣẹ́ púpọ̀ lórí SOO yìí, pàápàá jùlọ nínú Yorùbá Àjùmọ̀lò. Àwọn iṣẹ́ ìṣáájú ti dá lórí ìrísí SOO àti iṣẹ́ tí ó ń ṣe gan-an ní pàtó nínú ìhun gbólóhùn. Bámgbóṣé (1990: 180) àti Awóbùlúyì (1992: 32) dábàá pé ìrísí SOO nínú ìhun ìpìlẹ̀ gbólóhùn èdè Yorùbá àjùmọ̀lò ni '**ó',** gẹ́gẹ́ bí ó ti jẹyọ nínú àwọn àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ wọ̀nyí.

| | **Ìhun Ìpìlẹ̀** | | **Ìhun Òkè** |
|---|---|---|---|
| (1) | a. Ayọ̀ ó lọ sí ilé<br>Ayọ̀ SOO lọ sí ilé | → | Ayọ́ lọ sí ilé |
| | b. Délé ó ra bàtà<br>Délé SOO ra bàtà | → | Délé ra bàtà |
| | d. Igi ó wó dí ojú ọ̀nà<br>Igi SOO wo dí ojú ọ̀nà. | → | Igí wó dí ojú ọ̀nà |

Nínú àwọn àpẹẹrẹ òkè yìí, ní ìhun ìpìlẹ̀ ni a ti ṣe àfihàn ibi tí SOO ti jẹyọ láàárín olùwà àti ọ̀rọ̀ ìṣe. Ṣùgbọ́n tí a bá wo ìhun òkè, a ó ṣe àkíyèsí pé SOO ti parapọ̀ pẹ̀lú fáwẹ̀lì tó gbẹ̀yìn olùwà. Ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì tí ó wáyé ni pé a pa ìró fáwẹ̀lì èyí tí ó gba àmì ohùn SOO sórí jẹ èyí tí ó mú kí ohùn náà léfòó. Lẹ́yìn èyí ni ìsúnkì wáyé tí ìsóhùnnípò àti ìgbohùnnípò sì tẹ̀lé e. Pẹ̀lú lílo àpẹẹrẹ 1a, a ṣí àmì ohùn ìsàlẹ̀ tó wà lórí fáwẹ̀lì tó kẹ́yìn olùwà kúrò tí a sì fi àmì òkè gba ipò rẹ̀. Ìgbésẹ̀ yìí náà ló wáyé ní àwon àpẹẹrẹ tó kù. Ṣùgbọ́n ní 1b, ó ṣòro láti sọ àmì èyí tí a pa jẹ nínú SOO àti fáwẹ̀lì tó kẹ́yìn olùwà nítorí irú àmì ohùn kan náà ni wọ́n gbà sórí. Ní ti iṣẹ́ tí SOO ń ṣe nínú gbólóhùn, ẹnu àwọn

onímọ̀ ò kò nítorí èrò wọn ṣe ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀. Èyí ló jẹ́ kí wọ́n pè é ní oríṣiríṣi orúkọ. Bámgbóṣé (1967) àti Courtenay (1968) pe SOO ní atọ́ka kọ́ńkọ́ọ̀dù; Fresco (1970) gbàgbọ́ pé ó jẹ́ atọ́ka olùwà; Stahlke (1974) ṣe àfihàn rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí àfòmọ́ ìbẹ̀rẹ̀ kọ́ńkọ́ọ̀dù olùwà; Déchaine (1993) sọ pé ó jẹ́ atọ́ka ìbáṣepọ̀; Bisang àti Sonaiya (1999) rí i gẹ́gẹ́ bí wúnrẹ̀n tí ó ń sọ ìbáṣepọ̀ tí ó wà láààrín kókó gbólóhùn àti olùwà nínú gbólóhùn; Adéwọlé (1998) pè é ní àtamọ́; Awóbùlúyì (1975, 1978, 1992, and 2001), Olúmúyìwá (2009) àti Adéṣuyan (2006) rí i bíi wúnrẹ̀n aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe tí ó ń tọ́ka sí àsìkò afànámónìí. Nítorí èrò àti ìwòye àwọn onímọ̀ lóríṣiríṣi nípa iṣẹ́ SOO, Awóbùlúyì (1978: 49) gbèrò pé ó ṣeé ṣe kí ojútùú tó múná dóko má sí fún ìṣòro SOO ní èdè Yorùbá.

SOO tí à ń sọ̀rọ̀ rẹ̀ yìí kan náà máa ń jẹyọ nínú gbólóhùn ẹ̀ka èdè Arigidi. Àwọn onímọ̀ ìṣáájú ti pín ẹ̀ka èdè Arigidi, Arigidi jẹ́ ọ̀kàn lára àwọn ẹka èdè Yorùbá, tí wọ́n ń sọ ní àríwá ìwọ̀-oòrùn agbègbè Àkókó ní ìpínlẹ̀ Oǹdó (Oshodi 2011b). Arigidi jẹ́ orúkọ ìlú, bẹ́ẹ̀ sì ni ó tún jẹ́ orúkọ ẹ̀ka èdè tí wọ́n ń sọ ni ìlú Arigidi. Oshodi (2011) tí ó ṣiṣẹ́ lórí èdè Arigidi gbà pé SOO nínú èdè yìí ń ṣiṣẹ́ gẹ́gẹ́ bí atọ́ka àsìkò afànámónìí tàbí ìṣe tí ó ti parí. Àmọ́ ṣá, ẹ̀rí tuntun fi ìdí ẹ̀ múlẹ̀ pé SOO yìí máa ń jẹyọ papọ̀ pẹ̀lú atọ́ká àsìkò ọjọ́ iwájú nínú gbólòhùn èdè Arigidi. Tí SOO bá jẹ́ atọ́ka àsìkò afànámónìí lóòótọ́, a jẹ́ pé èyí yó sì tako ìmọ̀ kárí-ayé nípa èdè ọmọnìyàn pé gbólóhùn kan ṣoṣo ò lè sọ nípa àsìkò méjì ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀. Ìyẹn ni pé tí SOO bá jẹ́ atọ́ka àsìkò afànámọ́nìí, kò tún yẹ kí á rí atọ́ka àsìkò mìíràn mọ́ nínú gbólóhùn tó bá ti jẹyọ. Àmọ́ ẹ̀rí nínú àwọn gbólóhùn ìsàlẹ̀ wọ̀nyí fi hàn pé atọ́ka àsìko ọjọ́-iwájú tí a lo ìgékúrú KO fún jẹyọ pẹ̀lú SOO ní Arigidi.

| | | | | | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|
| (2). | Adé | á | ẹ̀ | we | → | Adé | ẹ́ | ẹ̀ | we |
| | Adé | SOO | KO | lọ | | Adé | SOO | KO | lọ |
| | ‘Adé yóò lọ’ | | | | | ‘Adé yóò lọ’ | | | |

| | | | | | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|
| (3). | Ṣadé | á | è | jeho | → | Ṣadé | é | ẹ̀ | jeho |
| | Ṣadé | SOO | KO | jẹun | | Ṣadé | SOO | KO | jẹun |
| | ‘Ṣadé á jẹun’ | | | | | ‘Ṣadé á jẹun’ | | | |

Tí ọ̀rọ̀ ba wá rí báyìí, a jẹ́ pé iyán ti dí àtúngún, ọbẹ̀ sì ti di àtúnsè. Ó ṣe pàtàkì kí a farabalẹ̀ wo ohun ti SOO jẹ́ gan-an ní èdè Arigidi. Nítorí náà, bébà yìí fẹ́ ṣe àtúnyẹ̀wọ sílébù olóhùn òkè ní èdè Arigidi.

**2. Tíọ́rì Àmúlò**

Tíọ́rì gírámá olófin ìyídà tí Chomsky (1981) ṣe agbáterù rẹ̀ ni a ṣe àmúlò rẹ̀ nínú bébà yìí. Tíọ́rì yìí fihàn pé ìbáṣepọ̀ wà láààrín orí, àmúpé, àfikún àti asọdọ̀tọ̀ nínú àpólà. Ìdí nìyí tí Haegeman (1998:104-105) fi sọ pé ara gírámà tí ó ń sàkóso ìhun àpólà ni a mọ̀ sí tíọ́rí onídàrọ olófin ìyídà. Orí àpólà lè jẹ́ ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ bí ọ̀rọ̀-orùkọ, ọ̀rọ̀-ìṣe, ọ̀rọ̀-arópò orúkọ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ, ó sì jẹ́ kanpá nínú ìhun àpólà nígbà tí àmúpé, àfikún àti asọdọ̀tọ̀ rẹ̀ si jẹ́ wọ̀fún.

Tíọ́rì gírámà onídàrọ olófin ìyídà tí a lò yìí ni èyí tí ó ṣe àgbékalẹ̀ ìyọrí abàárín ní ìṣàpéjúwé ìhun àpólà, pàápàá jùlọ láti ṣe ìyàtọ̀ láààrin àwọn fọ́nrán ìhun tó lè jẹyọ nínú apólà. Torí yìí ṣàfihàn ìhun àpólà bíi èyí tí ó ní ipele agajù, ipele abàárin àti ipele akérépin. Bí a ṣe máa ń ṣàpéjúwé àwọn ipele mẹ́tẹ̀ẹ̀ẹ̀ta yìí ní fihàn ní (4).

| | | | |
|---|---|---|---|
| (4). | $W^{II}$ | → | ìyọrí agajù |
| | $W^{I}$ | → | ìyọrí abàárín |
| | $W^{o}$/W | → | Ìyọrí akérépín/ori |

Ní (4), $Y^{II}$ dúró fún ìpele àpólà bí Àpólà Orúkọ (APOR), Apólà Ìṣe (APIṢ), Àpólà aṣẹ̀pọ́n

(APEP) àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. $Y^1$ dúró fún ìyọrí abàárín èyí tí ó jẹyọ láàárín ìpele àpólà àti ipele akérépin, tí $Y^o$ sì dúró fún ipele akérépin, èyí tí ó máa ń tọ́ka sí orí ọ̀rọ̀. Láti fi àwọn fọ́nrán ìhun inú àpọ́là hàn lórí àwọ̀rán atọ́ka ìgí, ìyọrí akérépin tí ó ń tọ́ka sí orí máa pàpọ̀ mọ́ ìhun àmúpé inú àpólà láti dí ìyọrí abàárín ($Y^I$); nígbà tí ìhun àfikún máa papọ̀ mọ́ ìyọrí abàárín láti dí ìyọrí abàárín mìíràn; tí ìhun asọdọ̀tọ̀ àti ìyọrí abàárín yó sì papọ̀ láti di ìyọrí agajù ($YP/Y^{II}$). Èyí ní a sọ ní ṣọ́kí ní nísàlẹ̀ yìí:

(5). $WP/W^{11} \rightarrow$ Asọdọ̀tọ̀, $W^I$
$W1 \rightarrow$ Àfikún, $W^I$
$W^1 \rightarrow$ Àmúpé, W tàbí $W^o$

Àlàyé ohun tí ó wà ní (5) ní a fi hàn ní àwòrán lórí atọ́ka igi báyìí:

(6).




(Taiwo, 2022)

**3. Sílébù Olóhùn Òkè ní Èdè Arigidi**

Gẹ́gẹ́ bí i ti èdè Yorùbá Àjùmọ̀lò, SOO máa ń jẹyọ láàárín àpólà orúkọ olùwà àti àpólà-ìṣe nínú gbólóhùn ní èdè Arigidi gẹ́gẹ́ bí ó ti fojúhàn nínú àwọn àpẹẹrẹ tí ó wà ní ìsàlẹ̀ wọ̀nyí.

(7). Bọ̀dé á we aja — 'Bọ̀dé lọ sí ọjà'
Bọ̀dé SOO lọ ọja

(8). Délé á yìnẹ́ — 'Délé sọ̀rọ̀'
Délé SOO sọ̀rọ̀

(9). Ayọ̀ á da bàtà — 'Ayọ̀ ra bàtà'
Ayọ̀ SOO ra bàtà

(10). Ọpẹ́ á kọ èjìn — 'Ọpẹ́ pọn omi'
Ọpẹ́ SOO pọn omi

(11). Á da tọntọn bàtà — 'Ó ra bàtà tuntun'
SOO ra tuntun bàtà

(12). Olú wọ̀nrin Ṣọlá wá jeho — 'Olú àti Ṣọlá jẹun'
Olú àti Ṣọlá **3ọ̀pọ̀+SOO** jẹun

(13). Wá we Èkó — 'Wọ́n lọ sí Èkó'
**3ọ̀pọ̀+SOO** lọ Èkó

Ní àwọn àpẹẹrẹ (4-10) tó wà lókè yìí, a rí i pé ìrísí SOO farahàn gẹ́gẹ́ bíi 'á' ní àpẹẹrẹ (4-8), ó sì

tún farahàn bíi 'wá' ní àpẹẹrẹ (9-10) níbi tí ó ti dàpọ̀ mọ́ arọ́pò orúkọ ẹnìkẹta ọ̀pọ̀. Tí a bá ti ibi ìṣáná kíyèsí òògùn nínú ìhun àwọn gbólóhùn yìí, a ó rí bátánì kan tó jọra nínú àwọn gbólóhùn ní ibi tí ìrísí SOO ti jẹ́ 'á'. Bátánì náà ni pé olùwà ọ̀kọ̀ọ̀kan inú àwọn gbólóhùn náà jẹ ẹyọ. Tí a bá sì tún kíyèsí àwọn gbólóhùn ní ibi tí ìrísí SOO ti jẹ́ 'wá', a rí i pé olùwà àwọn gbólóhùn náà jẹ́ ọ̀pọ̀. Pẹ̀lú bátánì tó fojùhàn yìí, ọ̀rọ̀ ti ń ní ojútùú bọ̀. Ṣùgbọ́n kí á tó fẹnu ọ̀rọ̀ jóná lórí ohun tí SOO jẹ́ ní ẹ̀ka èdè Arigidi, ẹ jẹ́ kí a wo àtẹ ọ̀rọ̀ arọ́pò orúkọ ní edè Arígidi tí ó wà ní ìsàlẹ̀ yìí, kí àṣìrí ọ̀rọ̀ yìí lè fojúhàn gbangba.

**Ọ̀rọ̀ Arọ́pò-Orúkọ Kúkúrú**

| Ipò olùwà | | | Ipò àbọ̀ | | |
|---|---|---|---|---|---|
| **Ẹni** | **Ẹ̀yọ̀** | **Ọ̀pọ̀** | **Ẹni** | **Ẹyọ** | **Ọ̀pọ̀** |
| **Kìn-ín-ní** | Ma | O | **Kìn-ín-ní** | Mi | Ò |
| **Kejì** | Ran | Mẹn | **Kejì** | Rin | Mẹ̀n |
| **Kẹta** | Ø | Wa | **Kẹta** | - | Wà |

Nínú àtẹ arọ́pò orúkọ tí ó wà lókè yìí, ibi tí ó kàn wá jù ni ọ̀rọ̀ arọ́pò orúkọ ẹnìkẹta ẹyọ àti ọ̀pọ̀ ní ipò olùwà. Arọ́pò orúkọ ẹnìkẹta ẹyọ ní ipò olùwà ṣófo nígbà tí arọ́pò orúkọ ẹnìkẹta ọ̀pọ̀ ní ipò olùwà jẹ́ 'wa'. Ìrísí arọ́pò orúkọ ẹnìkẹta ọ̀pọ̀ yìí jọ irísí SOO ní ibi tí olùwà ti jẹ́ ọ̀pọ̀. Ìyàtọ̀ tó wà láàárín wọn ni àmì ohùn. Ibi tí àṣírí òrọ̀ wà gan-an rè é. Àlàyé wà lórí sílébù olóhùn òkè ní Arígídi ni pé, SOO ń síṣẹ́ gẹ́gẹ́ bíi atọ́ka iye tí ó ń fi àbúdá iye olùwà inú gbólóhùn hàn. Níwọ̀n ìgbà tó jẹ́ pé arọ́pò orúkọ ní àbùdá iye tó ń fi ẹyọ àtí ọ̀pọ̀ hàn, ni SOO ṣe yàn án láti lè fi àbùdà iye olùwà hàn nínú gbólóhùn. SOO yìí máa ń gba ìrísí 'á' nígbà tí olùwà bá jẹ́ ẹyọ nítorí pé arọ́pò orúkọ ní ipò olùwà sófo nínú ẹ̀ka èdè Arigidi, gẹ́gẹ́ bí a ṣe fi hàn nínú àtẹ tó wà lókè. Torí náà a lè ṣàlàyé ìhun ìpìlẹ̀ àti ìhun òkè gbólóhùn ẹ̀ka èdè Arigidi báyìí.

(14) **Ìhun Ìpìlẹ̀** **Ìhùn Òkè**

a. Adé da bàtà
Adé SOO ra bàtà
'Adé ra bàtà.'

b. Adé á da bàtà
Adé SOO ra bàtà
'Adé ra bàtà.'

(15) **Ìhun Ìpìlẹ̀** **Ìhùn Òkè**

a. Họnhọn wó dí ojúdọ woro
IgiSOO wó dí ojú ọ̀nà
'Igi wó dí ojú ọ̀nà'

b. Họnhọn á wó dí ojúdọ woro
Igi SOO wó dí ojú ọ̀nà
'Igi wó dí ojú ọ̀nà'

(16) **Ìhun Ìpìlẹ̀** **Ìhùn Òkè**

a Ayọ̀ ́ sukọ̀ rupotu
Ayọ̀ SOO sáré jáde
'Ayọ̀ sáré jáde.'

b Ayọ̀ á sukọ̀ rupotu
Ayọ̀ SOO sáré jade
'Ayọ̀ sáré jáde.'

(17) **Ìhun Ìpìlẹ̀** **Ìhùn Òkè**

a Délé ́ rí wa
Délé SOO rí wọn
'Délé rí wọn'

b Délé á rí wa
Délé SOO rí wọn
'Délé rí wọn'

**Ìhun Ìpìlẹ̀** **Ìhùn Òkè**

(18). a Ọlá wọ̀nrin Ṣọlá wá web) Ọlá wọ̀nrin Ṣọlá wá we
Ọlá àti Ṣ 3pọ̀ SOO lọ Ọlá àti Ṣ **3pọ̀+SOO** lọ
'Ọlá àti Ṣọlá lọ' 'Ọlá àti Ṣọlá lọ'

(19). **Ìhun Ìpìlẹ̀**
a Àkùkù ọkọ́re wa ́ jo eṣẹn
gbogbo ọkùrin 3ọ̀pọ̀ SOO jẹ iṣu
'Gbogbo ọkùnrin jẹ iṣu'

**Ìhùn Òkè**
b Àkùkù ọkọ́re wá jo eṣẹn
Gbogbo ọkùnrin **3ọ̀pọ̀+SOO** jẹ iṣu
'Gbogbo ọkùnrin jẹ iṣu'

(20). **Ìhùn Òkè**
a Tádé wọ̀nrin Bọ́lá wa ́ ṣẹn ṣí ìyà
Tádé àti Bọ́lá 3ọ̀pọ̀ SOO sùn sí oko
'Tádé àti Bọ́lá sùn sí oko.'

**Ìhùn Òkè**
b Tádé wọ̀nrin Bọ́lá wá ṣẹn ṣí ìyà
Tádé àti Bọ́lá **3ọ̀pọ̀+SOO** sùn sí oko
'Tádé àti Bọ́lá sùn sí oko'

Nǹkan kan tí à ń pàkíyèsí wa sí nípa SOO nínú àwọn àpẹẹrẹ òkè yìí ni pé, SOO ń ṣàfihàn àbùdá iye olùwà dípò pé ó ń tọ́ká sí àsìkò afànámónìí nínú àwọn gbólóhùn náà. SOO yóò gba ìrísí 'á' nígbà tí olùwà bá jẹ́ ẹyọ, tí yóò sì gba ìrísí 'wá' nígbà tí olùwà bá jẹ́ ọ̀pọ̀. Láti tún gbe ẹ̀rí yìí lẹ́sẹ̀, ẹ jẹ́ kí a wo ìṣesí SOO nínú gbólóhùn ìṣẹ̀lẹ̀ àsìkò ọjọ́ ìwájú.

**4. SOO àti Atọ́ka Àsìkò Ọjọ́ Iwájú**

Atọ́ka àsìkò ọjọ́-ìwájú ni ó tọ́ka pé ìṣẹ̀lẹ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe inú gbólóhùn máa ṣẹ̀lẹ̀ ní ọjọ́-iwájú. Ìrísí atọ́ka àsìkò ọjọ́-iwájú ní ẹka èdè Arigidi ni 'ẹ̀'. Ìmọ̀ tí ó ti wà nílẹ̀ tẹ́lẹ̀ nípa SOO ní ẹ̀ka èdè Arigidi ní pé ó jẹ́ atọ́ka àsìkò afànámọ́nìí. Tí ó bá jẹ́ atọ́ka àsìkò afànámọ́nìí lóòótọ́, kó yẹ kí ó tún lè jẹyọ pẹ̀lú atọ́ka àsìkò mìíràn mọ́ torí pé gbólóhùn kan ṣoṣo o lè sọ nípa àsìkò méjì ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀. Èyí ni ó kọnilóminú nígbà tí a tún rí SOO tí ó jẹyọ pẹ̀lú atọ́ka àsìkò ọjọ́ iwájú nínú gbólóhùn ẹ̀ka èdè náà. Ohun tí a ṣàkíyèsí ni pé ìṣesí pẹ̀lú atọ́ka àsìkò ọjọ́ iwájú ní ẹ̀ka èdè Arigidi yàtọ̀ díẹ̀. Nínú Yorùbá Àjùmọ̀lò, SOO sábà máa ń gba ìrísí tàbí kí ó parapọ̀ mọ́ fáwẹ̀lì tó gbẹ̀yìn olùwà. Ṣùgbọ́n ní ẹ̀ka èdè Arigidi, nígbà tí SOO bá jẹyọ pẹ̀lú atọ́ka àsìkò ọjọ́ iwájú, ìrísí rẹ̀ máa ń farajọ ti atọ́ka àsìkò ọjọ́-iwajú tíí ṣe 'ẹ̀'. Ìyẹn ni pé kàkà kí ó gba ìrísí látí ara fáwẹ̀lì tó gbẹ̀yìn olùwà, ó máa ń gba ìrísí láti ara atọ́ka àsìkò ọjọ́-iwájú tó jẹyọ tẹ̀lé e ní apá ọ̀tún. Bóyá ìṣesí àrà ọ̀tọ̀ SOO ní ẹ̀ka èdè Arigidi yìí ló fà á tí àwọn onímọ̀ ìṣaájú ò ṣe kẹ́ẹ́fín pé SOO ni ó ń pa ìrísí dà. Àmọ́ ṣá, ẹ má gbàgbé pé a ti rí bátánì kan tí ó tú u láṣìírí, èyí tí a yànnàná saájú. Bátànì yìí ni yó máa ṣe atọ̀nà wa nígbà ti SOO bá fẹ́ farapamọ́. Torí náà, ohun tí à ń fidí rẹ̀ múlẹ̀ ni pé SOO máa ń jẹyọ pẹ̀lú atọ́ka àsìkò ọjọ́-iwájú ní ẹ̀ka èdè Arigidi gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú àwọn gbólóhùn ìsàlẹ̀ yìí.

(21) **Ìhun Ìpìlẹ̀**

a Ọláolúwa á ẹ̀ we
Ọláolúwa SOO KO lọ
'Ọláolúwa yóò lọ'

b **Ìhun Òkè**
Ọláolúwa ẹ́ ẹ̀ we
Ọláolúwa SOO KO lọ
'Ọláolúwa yóò lọ'

(22) **Ìhun Ìpìlẹ̀**

a. Ìfẹ́olúwa á ẹ̀ ṣọ ìgbẹ́ esin
Ìfẹ́olúwa SOO KO gbá náà ilẹ̀
'Ìfẹ́olúwa yóò gbá ilẹ̀ náà'

**Ìhun Òkè**

b Ìfẹ́olúwa ẹ́ ẹ̀ ṣọ ìgbẹ́ esin
Ìfẹ́olúwa SOO KO gbá náà ilẹ̀
'Ìfẹ́olúwa yóò gbá ilẹ̀ náà'

(23) **Ìhun Ìpìlẹ̀**

a Adé wọ̀nrin Bọ́lá wá ẹ̀ we
Adé àti Bọ́lá **3ọ̀pọ̀+SOO** KO lọ
'Adé àti Bọ́lá yóò lọ'
**Ìhun Òkè**

b Adé wọ̀nrin Bọ́lá wẹ́ ẹ̀ we
Adé àti Bọ́lá **3ọ̀pọ̀+SOO** KO lọ
'Adé àti Bọ́lá yóò lọ'

(24) **Ìhun Ìpìlẹ̀**

a Ọlá wọ̀nrin Adé wá ẹ̀ ṣẹn
Ọlá àti Adé **3ọ̀pọ̀+SOO** KO sùn
'Ọlá àti Adé á sùn'

b **Ìhun Òkè**
Ọlá wọ̀nrin Adé wẹ́ ẹ̀ ṣẹn
Ọlá àti Adé **3ọ̀pọ̀+SOO** KO sùn
'Ọlá àti Adé á sùn'

Tí a bá wo àwọn àpẹẹrẹ òkè yìí, 'ẹ̀' tí ó jẹ́ atọ́ka àsìkò ọjọ́-iwájú jẹyọ tẹ̀lé SOO. Ní àpẹẹrẹ, olùwà àwọn gbólóhùn náà jẹ́ ẹyọ, torí naa SOO ní ìhun ìpìlẹ̀ jẹ́ 'á' gẹ́gẹ́ bí atọ́ka ẹyọ bí a ti ṣàlàyé ṣaájú. Ṣùgbọ́n SOO 'á' yìí pa ìrísí dà ní ìhun òkè di 'ẹ́' nítorí atọ́ka àsìkò ọjọ́-iwájú 'ẹ̀' jẹyọ tẹ̀lé é. Bákan náà, ní àwọn àpẹẹrẹ (23-24), olùwà gbólóhùn náà pè ọ̀pọ̀, torí náà SOO 'wá' tí ó jẹ́ atọ́ka ọ̀pọ̀ wà ní ìhun ìpìlẹ̀, àwọn tí òun náà pa ìrísí dà ní ìhun òkè di 'wẹ́' nítorí atọ́ka àsìkò ọjọ́-iwájú 'ẹ̀' jẹyọ tẹ̀lé é.

Pẹ̀lú àwọn àpẹẹrẹ tí o wà lókè yìí, kò ní bójúmú láti pe SOO ní ẹ̀ka èdè Arigidi ní atọ́ka àsìkò afànámọ́nìí, àmọ́ bátánì tí ó fojúhàn ti bá wa wá ojútùú sí ọ̀rọ̀ yìí pè SOO ń fi àbùdá iye hàn ni, torí náà ni a ṣe pè é ni atọ́ka iye.

**5. SOO Pẹ̀lú Àwọn Atọ́ka Yòókù**

Bí a ṣe sàlàyé ìṣesí SOO pẹ̀lú atọ́ka àsìkò ọjọ́ iwájú, a tún fẹ́ wo ìṣesí rẹ̀ pẹ̀lú àwọn atọ́ka yòókù bíi atọ́ka ibá-iṣẹ̀lẹ̀ atẹ́rẹrẹ, atọ́ka ibá-iṣẹ̀lẹ̀ aṣetán, atọ́ka ibá-iṣẹ̀lẹ̀ abárakú àti atọ́ka ìyísodì.

**5.1. SOO àti Atọ́ka Ibá-Ìṣẹ̀lẹ̀ Atẹ́rẹrẹ**

Ibá-ìṣẹ̀lẹ̀ atẹ́rẹrẹ ń tọ́ka sí ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó ń lọ lọ́wọ́ ní àkókò tí a ń ṣafọ̀. Atọ́ka ibá-ìṣẹ̀lẹ̀ atẹ́rẹrẹ ní Arigidi ni 'sà'. SOO tí à ń gbéyẹ̀wò yìí máa ń jẹyọ nínú gbólóhùn ibá-ìṣẹ̀lẹ̀ atẹ́rẹrẹ, tí ó sì ń fi bátánì àbùdá iye hàn gẹ́gẹ́ bí a ti sàlàyé ṣaájú. Ẹ jẹ́ kí á wo ìjẹyọpọ̀ SOO àti atọ́ka iba-ìṣẹ̀lè atẹ́rẹrẹ nínú àwọn àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ wọ̀nyí.

(25) Ìfẹ́olúwa á sà jo eṣẹn ìwásùn gẹlẹgẹlẹ
Ìfẹ́olúwa SOO IB jẹ iṣu díndín lọ́wọ́
'Ìfẹ́olúwa ń jẹ iṣu díndín lọ́wọ́'

(26) Délé á sà yìnẹ́ gẹlẹgẹlẹ ojú agbo
Délé SOO IB sọ̀rọ̀ lọ́wọ́ ojú agbo
'Délé ń sọ̀rọ̀ lọ́wọ́ ní ojú agbo'

(27) Àkùkù ọkọ́re wá sà jọdan gẹlẹgẹlẹ oso
Gbogbo ọkùnrin **3ọ̀pọ̀+SOO** IB ṣiṣẹ́ lọ́wọ́ ilé
'Gbogbo ọkùnrin ń ṣiṣẹ́ lọ́wọ́ ní ilé'

(28) Òjó wọ̀nrin Títí wá sà kọ èjin gẹlẹgẹlẹ
Òjó àti Títí **3ọ̀pọ̀+SOO** IB pọn omi lọ́wọ́
'Òjó àti Títí ń pọn omi lọ́wọ́'

Ní àwọn àpẹẹrẹ tí ó wà ní 25-26 lókè yìí, 'sà' tí ó jẹ́ atọ́ka ibá-ìṣẹ̀lẹ̀ atẹ́rẹrẹ jẹyọ tẹ̀lé SOO. Tí a bá wo àwọn àpẹẹrẹ wọ̀nyẹn, olùwà àwọn gbólóhùn náà jẹ́ ẹyọ , SOO ní ìhun náà jẹ́ 'á' gẹ́gẹ́ bí atọ́ka ẹyọ gẹ́gẹ́ bí a ti ṣe sọ ṣaájú. Ṣùgbọ́n ní àpẹẹrẹ 27-29, olùwà àwọn gbólóhùn náà jẹ́ ọ̀pọ̀, torí náà SOO 'wá' tí ó jẹ́ atọ́ka ọ̀pọ̀ ni ó jẹyọ tẹ̀lé olùwà ọ̀pọ̀. Ìmọ̀ tí ó ti wà nílẹ̀ nípa SOO (Oshodi 2011) ní ẹ̀ka èdè Arigidi ni pé ó jẹ́ atọ́ka ìṣe tí ó ti parí (èyí tí a le túmọ̀ sí ibá-ìṣẹ̀lẹ̀ aṣetán). Tí ó bá jẹ́ lóòótọ́ ni kò yé kí SOO tún lè jẹyọ pẹ̀lú atóka ibá-ìṣẹ̀lẹ̀ atẹ́rẹrẹ gẹ́gẹ́ bí ó ti hàn nínú àwọn àpẹẹrẹ tí ó wà lókè yìí.

Pẹ̀lú ẹ̀rí yìí, a rí i pé àṣìṣe ni láti sọ pé SOO ní ẹka èdè Arigidi jẹ́ atọ́ka ìṣe tí ó ti parí. Ṣùgbọ́n iṣẹ́ gbòógì tí SOO ń ṣe ni pé ó ń fi àbùdá iye hàn ni.

**5.2. SOO àti Atọ́ka Ibá-Ìṣẹ̀lẹ̀ Àsetán**

Ibá-ìṣẹ̀lẹ̀ Àṣetán ń sọ nípa ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó ti parí ní àkókò tí a ń ṣafọ̀. Atọ́ka ibá-ìsẹ̀lẹ̀ Àṣetán ní Arigidi ni 'a'. Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ ṣaájú SOO ní Arigidi kì í ṣe atọ́ka ibá-ìṣẹ̀lẹ̀ Àṣetán, ìrísí wọn lè jọra, àmọ́ ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni wọn. Àwọn àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ wọ̀nyí ṣàfihàn ìṣesí SOO pẹ̀lú àtọ́ka ibá-ìṣẹ̀lẹ̀ Àṣetán nínú gbólóhùn èdè Arigidi.

(29) Ṣọlá á a jeho tán tipẹ́tipẹ́
Ṣọlá SOO IB jẹun tán tipẹ́tipẹ́
'Ṣọlá ti jẹun tán tipẹ́tipẹ́'

(30) Délé á a pọ tí ìgbẹ́ ìṣẹ̀lẹ̀
Délé SOO IB dé síwájú náà ìṣẹ̀lẹ̀
'Délé ti dé síwájú ìṣẹ̀lẹ̀ náà'

(31) Ṣadé á a yìnẹ́ tipẹ́tipẹ́
Ṣadé SOO IB sọ̀rọ̀ tipẹ́tipẹ́
'Ṣadé ti sọ̀rọ̀ tán tipẹ́tipẹ́'

(32) Àkùkù ọkọ́re wá a ṣẹn ṣí ìyà
Gbogbo ọkùnrin **3ọ̀pọ̀+SOO** IB sùn sí oko
'Gbogbo ọkùnrin ti sùn sí oko'

(33) Ayọ̀ wọ̀nrin Olú wá a pọ Èkìtì ìni ura
Ayọ̀ àti Olú **3ọ̀pọ̀+SOO** IB dé Èkìtì láti àná
'Ayọ̀ àti Olú ti dé Èkìtì láti àná'

Tí a bá wo àwọn àpẹẹrẹ (29-33) òkè wọ̀nyí, ó fojú hàn gbangba pé atọ́ka ibá-ìsẹ̀lẹ̀ asetán yàtọ̀ sí SOO, wọ́n sì jẹyọ tẹ̀lé ara wọn nínú àwọn gbólóhùn náà.

**5.3. SOO àti Atọ́ka Ibá-Ìṣẹ̀lẹ̀ Bárakú**

Ibá-ìṣẹ̀lẹ̀ Bárakú ni èyí tí ó ń júwe ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó ti di àṣà tàbí ìṣe tí ó ti mọ́ra. Atọ́ka ibá-ìṣẹ̀lẹ̀ Bárakú ní Arigidi ni 'sì'. SOO tún máa ń jẹyọ pẹ̀lú atọ́ka ibá-ìṣẹ̀lẹ̀ Bárakú nínú gbólóhùn èdè Arigidi. Ẹ jẹ́ kí á wo ìsesí SOO pẹ̀lú atọ́ka ibá-ìṣẹ̀lẹ̀ Bárakú nínu àwọn àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ wọ̀nyí.

(34) Bùsáyọ̀ á sì wa ìgbẹ́ mọ́tò àlàlátù
Bùsáyọ̀ SOO IB wa náà mọ́tò àràárọ̀
'Bùsáyọ̀ a máa wa ọkọ̀ náà ní àràárọ̀'

(35) Tọ́láni á sì yìnẹ́ àkùkúfọ̀
Tọ́láni SOO IB sọ̀rọ̀ gbogbo
'Tọ́láni máa ń sọ̀rọ̀ nígbà gbogbo'

(36) Ṣadé wọ̀nrin Bọ́lá wá sì kọ èjin àlàlátù
Ṣadé àti Bọ́lá **3ọ̀pọ̀+SOO** IB pọn omi àràárọ̀
'Ṣadé àti Bọ́lá máa ń pọn omi ní àràárọ̀'

Tí a bá wo àwọn àpẹẹrẹ tí ó wà ní (34-36), 'sì' ní atọ́ka ibá-ìṣẹ̀lẹ̀ Bárakú, ó sì ń ṣe àfihàn ìṣe tí ó ti di àṣà tàbí bárakú. Gẹ́gẹ́ bí a ṣe ń ṣàlàyé látẹ̀yìnwá, SOO mú ìrísí 'á' tí ó ṣàfihàn ẹyọ nítorí olùwà nínú àwọn gbólóhùn náà jẹ́ ẹyọ, ṣùgbọ́n ní àwọn àpẹrẹ tó kù, ìrísí SOO jẹ́ 'wá' tí ó ṣàfihàn ọ̀pọ̀ nítorí olùwà àwọn gbólóhùn náà jẹ́ ọ̀pọ̀.

**5.4. SOO àti Atọ́ka Ìyísódì**

Atọ́ka ìyísódì ní ẹka èdè Arigidi ni 'kà'. Àmọ́ ṣá, a máa ń pa ìró kọ́ńsónáǹtì 'k' ara atọ́ka yìí jẹ nígbà tí a bá n ṣafọ̀ tí yóò sì ku fáwẹ̀lì 'à' nìkan. Nínú gbólóhùn ẹ̀ka èdè Arigidi, SOO tún máa ń jẹyọ pẹ̀lú atọ́ka ìyísódì. Àwọn àpẹẹrẹ ìṣàlẹ̀ yìí ṣàfihàn ìṣesí SOO àti atọ́kà ìyísódì nínú ìhun gbólóhùn.

(37)a. **Ìhun Ìpìlẹ̀**
Ṣadé á kà we
Ṣadé SOO OD lọ
'Ṣadé kò lọ'

b. **Ìhun Òkè**
Ṣadé á à we
Ṣadé SOO OD lọ
'Ṣadé kò lọ'

(38)a. **Ìhun Ìpìlẹ̀**
Adé á kà da bàtà
Adé SOO OD ra bàtà
'Adé kò ra bàtà.'

b. **Ìhun Òkè**
Adé á à da bàtà
Adé SOO OD ra bàtà
'Adé kò ra bàtà'

(39)a. **Ìhun Ìpìlẹ̀**
[APOR] á kà we
SOO OD lọ
'Kò lọ'

b. **Ìhun Òkè**
[APOR] á à we
SOO OD lọ
'Kò lọ'

(40)a. **Ìhun Òkè**
Ọlá wọ̀nrin Adé wá kà po esọ
Ọlá àti Adé **3ọ̀pọ̀SOO** OD pa ẹja
'Ọlá àti Adé kò pa ẹja.'

b. **Ìhun Òkè**
Ọlá wọ̀nrin Adé wá à po esọ
Ọlá àti Adé **3ọ̀pọ̀SOO** OD pa ẹja
'Ọlá àti Adé kò pa ẹja'

Nínú gbólóhùn ìyísódì (37-40) tí ó wà lókè yìí, SOO ń ṣàfihàn àbúdá iye olùwà bákan náà.`kÀwọn àpẹẹrẹ náà tún fi idí ẹ̀ múlẹ̀ pé kànńpá ni láti pa ìró kọ́ńsónáńtì [k] ara atọ́ka ìyísódì jẹ ní ẹka èdè Arigidi. Ìrísí atọ́ka ìyísódì ní kíkún sáábà máa ń jẹyọ nínú gbólóhùn ìtenumọ́ gẹ́gẹ́ bí ó ti hàn nínú àwọn àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí.

(41)a. **Gbólóhùn Ìpìlẹ̀**
Adé wọ́n we
Adé IT lọ
'Adé ni ó lọ.'

b. **Gbólóhùn Ìtẹnumọ́**
Adé wọ́n kà we
Adé IT OD lọ
'Adé kọ́ ni ó lọ'

(42)a. **Gbólóhùn Ìpìlẹ̀**
Ámẹ wọ́n we
Emi IT lọ
'Èmi ni ó lọ'

b. **Gbólóhùn Ìtẹnumọ́**
Ámẹ wọ́n kà we
Èmi IT OD lọ
'Èmi kọ́ ni ó lọ'

**6. SOO Àti Ọ̀rọ̀ Arọ́pò-Orúkọ**

Gẹ́gẹ́ bí àlàyé wá lórí SOO ní Arigidi ṣe fojúhàn pé SOO máa ń ṣiṣẹ́ pọ̀ pẹ̀lú arọ́pò orúkọ láti fi abùdá iye han, torí náà bí olùwà inú gbólóhùn bá jẹ́ ọ̀rọ̀ arọ́pò orúkọ,ohùn òkè yóò jẹyọ tààrà lórí arọ́pò orúkọ náà. Ẹ jẹ́ kí á wo àwọn àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ wọ̀nyí:

(43) **Ìhun Ìpìlẹ̀** → **Ìhun òkè**
Ma ´ we → Má we 'Mo lọ'
1ẹyọ SOO lọ → **1ẹyọ+SOO** lọ

(44) O ´ we → Oá we 'A lọ'
1ọ̀pọ̀ SOO lọ → **1ọ̀pọ̀+SOO** lọ

(45) Mẹn ´ we → Mẹ́n we 'Ẹ lọ'
2ọ̀pọ̀ SOO lọ → **2ọ̀pọ̀+SOO** lọ

(46) Ø Á we → Á we 'Ó lọ'
3ẹyọ SOO lọ → SOO lọ

(47) Wa ´ we → Wá we 'Wọ́n lọ'
3ọ̀pọ̀ SOO lọ → **3ọ̀pọ̀+SOO** lọ

**7. SOO Nínú Gbólóhùn Àkíyèsí Alátẹnumọ́**

Atọ́ka gbólóhùn àkíyèsí alátẹnumọ́ ní ẹ̀ka èdè Arigidi ni '*wọ́n'* èyí tí ó sábàá máa jẹyọ tẹ̀lé wúnrẹ̀n tí a ṣe ìtẹnumọ́ fún. Ohun tí a ṣàkíyèsí ni pé SOO kì í jẹyọ nínú ìhun gbólóhùn àkíyèsí alátẹnumọ́ yìí ní ẹ̀ka èdè Arigidi. Oshodi (2011) gbà pé èyí rí bẹ́ẹ̀ nítorí ìhun gbólóhùn àkíyèsí alátẹnumọ́ fúnra rẹ̀ ń sọ nípa ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó ti kọjá, tí SOO náà sì jẹ́ atọ́ka àsìkò afánamọ́nìí. Àmọ́ ṣá, ẹ̀rí tuntun tí a rí tako èrò yìí nítorí gbólóhùn àkíyèsí alátẹnumọ́ le sọ nípa ìṣẹ̀lẹ̀ ọjọ́ iwájú gẹ́gẹ́ bí ó ti hàn nínú àwọn àpẹẹrẹ wọ̀nyí.

(48) Ìyà wọ́n Adé ẹ̀ sẹ̀n
Oko IT Adé KO sùn
'Oko ni Adé á sùn'

(49) Eṣẹn ìwásùn wọ́n Ọlá ẹ̀ jo
Iṣu díndín IT Ọlá KO jẹ
'Iṣu díndín ni Ọlá á jẹ'

Ní àpẹẹrẹ (48-49) tó wà lókè yìí, atọ́ka àsìkò ọjọ́ iwájú 'ẹ̀' èyí tí a lo àrokò KO fún jẹyọ nínú gbólóhùn àkíyèsí alátẹnumọ́. Èyí ń fidí ẹ múlẹ̀ pé gbólóhùn àkíyèsí alátẹnumọ́ kì í sọ nípa ìṣẹ̀lẹ̀ tó ti kọjá nìkan gẹ́gẹ́ bíi èrò tó ti wà nílẹ̀, àmọ́ tí ó ń sọ nípa ìṣẹ̀lẹ̀ ọjọ́ iwájú.

Àmọ̀ síbẹ̀síbẹ̀, SOO kò sì jẹyọ nínú ìhun gbólóhùn àkíyèsí alátẹnumọ́ ní Arigidi. Ẹ má gbàgbé pé a sọ pé SOO ní Arigidi ń ṣiṣẹ́ papọ̀ pẹ̀lú ọ̀rọ̀ arọ́pò orúkọ láti fi àbúdà iye olùwà hàn ni. Àlàyé wa fún àìjẹyọ rè nínú ìhun gbólóhùn àkíyèsí alátẹnumọ́ ni pé, SOO ni Arigidi ní ìtumọ̀ ìtẹnumọ́. Èyí ló fà á tí kì í fi jẹyọ nínú ìhun gbólóhùn àkíyèsí alátẹnumọ́.

(50) Eṣẹn wọ́n Ṣọlá da
Iṣu IT Ṣọlá rà
'Iṣu ni Ṣọlá rà'

(51) Adé wọ́n da bàtà
Adé IT ra bàtà
'Adé ni ó ra bàtà '

(52) Tọ́lání wọnrìn Bọ́lá wọ́n we
Tọ́lání àti Bọ́lá IT lọ
'Tọ́lání àti Bọ́lá ni wọ́n lọ'

**8. Fífi Tíọ́rì Ṣàlàyé Ipò SOO Nínú Ìhun Gbólóhùn**

Sílébù olóhùn òkè máa ń jeyọ láàárín àpólà orúkọ olùwà àti àpólà ìṣe nínú gbólóhùn. Nínú tíọ́rì olófin ìyídà tí a lò nínú bébà yìí, Apàrísídà (APAPR) ni ó ń ṣàlàyé ìhun gbólóhùn, tí àwọn wúnrẹ̀n bí atọ́ka àsìkò, ibá-ìṣẹ̀lẹ̀ àti ìyísódì sì máa ń wà ní ipò orí nínú APAPR. Àlàyé wa nínú bébà yìí ni pé SOO jẹ́ ọ̀kan lára wúnrẹ̀n tí ó ń jẹyọ ní ipò orí APAPR àmọ́ tí ó ṣiṣẹ́ láti fi àbùdá iye hàn. Ohun tí a fìdí rẹ̀ múlẹ̀ nínú bébà yí ni pé SOO yó mú ìrísí 'á' nígbà tí olùwà inú gbólóhùn bá jẹ ẹyọ, tí ìrísí rẹ̀ yó sì jẹ́ 'wá', nígbà tí olùwà gbólóhùn bá jẹ́ ọ̀pọ̀. A lo àpẹẹrẹ (53) àti (54) ìsàlẹ̀ yìí láti fi ipò SOO hàn nínú gbólóhùn lórí àwòrán atọ́ka igi.

(53). Délé á ẹ̀ da mọ́tò




(54). Àkùkù ọkọ́re wá jo eṣẹn




Nínú àwọn àwòrán atọ́ka-igi (53 & 54) tí ó wà lókè wọ̀nyí, a ó ṣe àkíyèsí pé SOO àti atọ́ka àsìkò jẹyọ̀ lọ́tọ̀ọ̀tọ̀ ní ipò orí APAPR. Ohun ti èyì ń ṣàlàyé ni pé bí ó tílẹ̀ jé pé wúnrẹ̀n méjèèjì jeyọ ní ipò orí, wọn kìí ṣe ọ̀kanùn. Àlàyé yìí fojúhàn gbàngba ní (53) ní ibi ti SOO 'á' ti jẹyọ pẹ̀lú atọ́ka àsìkò ọjọ́ iwájú 'ẹ̀' ní ìyọrí akérépin. Bákan náà ní ọmọ ṣe orí ní àpẹẹrẹ (53). Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àsìkò afànámónìí farasin, àmọ́ èyí ò ní pé SOO jẹ́ àsìkò. Ààyè ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni wọ́ wà ní ìyọrí akérépin. Ojú ọ̀run tó ẹyẹ fò láì fárakanra ni ọ̀rọ̀ ọ̀hún. Bí SOO ṣe le jẹyọ ní ààyè ọ̀tọ̀ náà ni atọ́ka àsìkò àti àwọn wúnrẹ̀n mìíràn bí atọ́ka ibá-ìṣẹ̀lẹ̀ àtí ìyísódì lẹ jẹyọ ní ipò akérépin APAPR láì dí ara wọn lọ́wọ́.

**9. Ìgúnlẹ̀**

Oríṣiríṣi ojú ni àwọn onímọ̀ ti fi wo iṣẹ́ tí sílẹ́bù olóhùn òkè ń ṣe nínú gbólóhùn pàápàá jùlọ nínù èdè Yorùbá Àjùmọlò. Ọ̀rọ̀ ọ̀hún dàbí ìlù gángan tó jẹ́ pé bí ó ti kọ ojú sí ẹnìkan, ẹ̀yìn ló kọ sí ẹlòmíìn. Sílèbù olóhùn òkè yìí kan náà jẹyọ nínú ìhun gbólóhùn ẹ̀ka èdè Arigidi, èyí tí àwọn onímọ̀ ìṣáájú pè ní atọ́ka àsìkò afànámónií tàbí wúnrẹ̀n tí ó ń tọ́ka sí ìṣẹ̀lẹ̀ tó ti parí. Àmọ́ ẹ̀rí tuntun tí a yànnàná nínú ìwé yìí fi idí rẹ̀ múlẹ̀ pé wúnrẹ̀n yìí kì í ṣe ohun tí àwọn onímọ̀ ìṣáájú pè é. Àlàyé wa nínú bébà yìí ni pé sílébù olóhùn òkè ń ṣiṣẹ́ pọ̀ pẹ̀lú arọ́pò orúkọ láti fi àbùdá iye olùwà inú gbólóhùn hàn. Èyí ló jẹ́ kí ìrísí wúnrẹ̀n náà jẹ́ 'á' nígbà ti olùwà inú gbólóhùn bá jẹ́ ẹyọ, tí yó sì jẹ́ 'wá' nígbà ti olùwà inú gbólóhùn bá jẹ́ ọ̀pọ̀.

**Àwọn Ìwé Ìtóka̩sí**

Awóbùlúyì, O. (1975) On the subject Concord Prefix in Yorùbá. *Studies in African Linguistics* 6: 215– 238

Awóbùlúyì, O. (1978) *Essentials of Yoruba Grammar. Ìbàdàn*: Oxford University Press.

Awóbùlúyì, O. (1992) Aspects of Contemporary Standard Yorùbá in Dialectological Perspective. In: Akínwùnmì Ìshọ̀lá (ed.), *New Findings in Yorùbá Studies*. J. F. Odúnjọ Memorial Lectures Organising Committee.

Awóbùlúyì, O. (2001) Arọpò-Orúkọ kúkúrú Ẹni kẹta Ẹyọ Asolùwà. *Yorùbá: Journal of the Yorùbá Association of Nigeria* 2(1): 1–8.

Bámgbóṣé, A. (1967) *A short Yorùbá Grammar*. Heinemann Educational Books.

Olúmúyìwá, O.T. (2009) The High Tone Syllable in Central Yorùbá Dialects. *Nordic Journal Of African Studies* 18(2): 129–137.

Oshodi, B. (2010) Atọ́ka Àsìkò ati Ibá-Ìṣẹ̀lẹ̀ nínú Èdè Arigidi. *Inquiry in African Languages and Literatures* 2010(7): 1–9.

Oshodi, B. (2011a) The HTS (High Tone Syllable) in Arigidi: An Introduction. *Nordic Journal of African Studies* 2011(4): 263–275.

Oshodi, B. (2011b) The Sociolinguistics of Borrowing: The Impact of Yorùbá on Arigidi. *UNAD Studies in Language and Literature* 2011, 4(1): 209–231.

Oshodi, B. (2011c) *A Reference Grammar of Arigidi*. Montem Paperbacks, Akure Nigeria.

Oyenike, C. A. (2021) Negation In The Arigidi Dialect Of Ǹjọ̀– Kóo Language. M.A Thesis. Department of Linguistics and African Languages. University of Ibadan.